# Àgbéyẹ̀wò Ipa àti Ipò Àwọn Ọmọdé Nínú Ìpohùn Òrìṣà Ẹgbẹ́ Ọ̀gbà ní Agbègbè Yewa-Awórì, Ẹ̀gbá, àti Ìjẹ̀bú

Sauban Alade Ishọla
Department of Yorùbá Studies,
Tai Solatrin University of Education, Ìjagun,
Ògùn State, Nigeria
isholasauban@gmail.com

## Àṣamọ̀

Onírúurú ìwádìí ló ti wáyé nípa ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá, ṣùgbọ́n, iṣẹ́ kò tíì pọ̀ lórí ipa àti ipò àwọn èwe nínú àjọ̀dún ìbílẹ̀ Yorùbá. Iṣẹ́ yìí lo àkójọ-èdè-fún-àyẹ̀wò láti inú Òrìṣà Ẹgbẹ́ tí ó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn Òrìṣà èwe ní agbègbè Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú ní ìpínlẹ̀ Ògùn láti ṣe àwárí ìmọ̀ lóri abala ibi tí iṣẹ́ àwọn onímọ̀ ìṣáájú kò tíì dé nínú lítíréṣọ̀ ọmọdé. Ìlànà tí a gbà ṣe iṣẹ́ ìwádìí yìí ni ṣíṣe àkójọ àwọn ìpohùn tí ó jẹ mọ́ Òrìṣà Ẹgbẹ́ ní agbègbè Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. A ṣe ìwádìí lọ́dọ̀ àwọn èwe tí wọ́n jẹ́ olùsìn àwọn Òrìṣà Ẹgbẹ́ yìí ní agbègbè Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. A tún ṣe ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò fún àwọn akópa tí wọ́n jẹ́ àgbààgbà olùsìn Òrìṣà Ẹgbẹ́ náà lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan, a sì ká a sílẹ̀ nínú fọ́nrán àti fídíò. A tún ṣe àyẹ̀wò ìwé àpilẹ̀kọ, jọ́nà àti ẹ̀rọ-ayélujára lórí oríṣìí àwọn iṣẹ́ ìwádìí tó jẹ mọ́ lítíréṣọ̀ alohùn àwọn ọmọdé. Àwọn Ìpohùn tí a gbà jọ ní oko ìwádìí ni a ṣe ìtúpalẹ̀ wọn ní ìbámu pẹ̀lú àfojúsùn àwọn agbátẹ̀rù ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì ti Amber àti Haque (2004). Iṣẹ́ yìí ṣe àyẹ̀wò ipò tí àwọn Yorùbá fi àwọn ọmọ wọn sí nínú ọdún ìbílẹ̀. Bákan náà ẹ̀wẹ̀, iṣẹ́ yìí ṣe àyẹ̀wò ipa tí àwọn èwe àwùjọ Yorùbá ń kó nínú ìgbékalẹ̀ ọdún ìbílẹ̀ Òrìṣà Ẹgbẹ́ láwùjọ àwọn Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá and Ìjẹ̀bú. Iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, ipò pàtàkì ni ọdún ìbílẹ̀ yìí wà nínú ètò ìgbé ayè àwọn olùsìn rẹ̀, tí wọ́n fi ń darí èròǹgbà wọn lórí ìfọkàntán, òtítọ́ ṣíṣe, ìdájọ́-òdodo, ìjúbà, dídarí-ẹ̀mí wọn sí Òrìṣà Ẹgbẹ́ àti ìgbàgbọ́ wọn nínú àyànmọ́. Iṣẹ́ yìí tún ṣe àfihàn àwọn ìdí pàtàkì tí wọ́n fi ń ṣe ọdún ìbílẹ̀ fún Òrìṣà Ẹgbẹ́ gẹ́gẹ́ bí èyí tí wọ́n

gbé àwọn ìpohùn inú rẹ̀ kalẹ̀ fún ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn, ìwà ọmọlúàbí, àṣà àti ìṣe pẹ̀lú oríṣìí àwọn ìlànà ìbara-ẹni-gbépọ̀ fún àwọn ọmọ wọn.

## Ìfáárà

Ìwádìí kò tíì pọ̀ lórí àwọn lítíréṣọ̀ tó wà fún àwọn ọmọdé láwùjọ Yorùbá. Èyí fara hàn nínú ìwádìí tí a ṣe lórí àwọn ewì alohùn tí wọ́n ṣẹ̀dá láti máa fi kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀sìn, ìwà ọmọlúàbí, iṣẹ́-ọnà àti oríṣìí àwọn ẹ̀kọ́ mìíràn ní ilẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú ní Ìpínlẹ̀ Ògùn. Àwọn onímọ̀ tí wọ́n ti ṣe ìwádìí nípa lítíréṣọ̀ ọmọdé ni a rí i pé abala ewì alohùn tí ó wà fún ìdárayá àti ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ àwùjọ. Iṣẹ́ kò tíì pọ̀ lórí àwọn ewì alohùn ajẹmọ́-ẹ̀sìn tó wà fún àwọn èwe ní agbègbè Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. Èyí ni àlàfo tí ìwádìí yìí gbèrò láti dí.

Èròǹgbà iṣẹ́ yìí ni àfihàn akitiyan àwọn Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú lórí ìgbékalẹ̀ àwọn Òrìṣà èwe ní àwùjọ wọn tí wọ́n ń lò fún ẹ̀sìn, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ìdánilárayá àti ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ àwùjọ wọn lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan. A yan Òrìṣà Ẹgbẹ́ láàyò nínú àwọn Òrìṣà náà, nítorí pé ó jẹ́ èyí tó gbajúmọ̀ ní gbogbo agbègbè tí a ti ṣe ìwádìí. A tún rí i pé, púpọ̀ nínú àwọn ohun tí a gbèrò láti fi ṣe òd-iwọ̀n ìwádìí wa ló hàn nínú àkóónú Òrìṣà Ẹgbẹ́ tí a yàn láàyò yìí. Àwọn ìpohùn ọmọdé tó wà láwùjọ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú lè jẹ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn, ó sì tún lè jẹ́ èyí tó ń ṣú yọ nínú àgbékalẹ̀ eré ìdárayá tàbí èyí tó ń wáyé nínú onírúurú ayẹyẹ láwùjọ wọn. Gbogbo ìsọ̀rí àwọn ewì náà ni a ti rí àpẹẹrẹ ìlànà ètò-ẹ̀kọ́ àwùjọ wọn, gẹ́gẹ́ bí èròǹgbà tí wọ́n ní láti máa lò wọ́n fún ẹ̀sìn, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ìdánilárayá àti ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ àwùjọ wọn lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan. Bí àwọn àgbààgbà ti ní lítíréṣọ̀ alohùn tiwọn, ní èyí tí ó lè jẹ mọ́ ẹ̀sìn, ayẹyẹ àti àwọn oríṣìí mìíràn bẹ́ẹ̀, ni wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ àwọn lítíréṣọ̀ alohùn kan fún àwọn ọmọdé. Èròǹgbà tí wọ́n ní lórí àgbékalẹ̀ àwọn lítíréṣọ̀ tí wọ́n ṣẹ̀dá wọn fún àwọn ọmọdé ni pé, wọ́n ń lò wọ́n láti kọ́ wọn ní ẹ̀kọ́ tí yóò wúlò fún wọn tí wọ́n bá dàgbà. Èròǹgbà wọn dàbí òwe Yorùbá tí ó sọ pé, kékeré là á ti í pa èèkàn ìrókò, kí ó tó dàgbà máa gbẹbọ lọ́wọ́ ẹni. Bákan náà ni wọ́n gbàgbọ́ pé, Òrìṣà tí a kò fi ìdí rẹ̀ han ọmọdé, ó máa ń parun ni. Ìdí nìyí, tí wọ́n fi yan onírúurú ojúṣe fún àwọn ọmọdé nínú àgbékalẹ̀ ìbọ àwọn Òrìṣà Èwe tó wà ní àwùjọ wọn.

Àrokò tí àwọn Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú ń fi ojúṣe àwọn ọmọdé pa nínú ẹ̀sìn ìbílẹ̀ àwùjọ wọn jẹ mọ́ kíkọ́ wọn ní ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí, èdè àti onírúurú àwọn ẹ̀kọ́ mìíràn tó ṣodo sínú àwọn lítíréṣọ̀ alohùn tí wọ́n ṣẹ̀dá fún àwọn ọmọ náà. Nítorí náà, a gbàgbọ́ pé àwọn Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí wọ́n wà ní Ìpínlẹ̀ Ògùn náà ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ewì alohùn tí a yàn fún òdiwọ̀n iṣẹ́ ìwádìí wa yìí láti kọ́ àwọn ọmọ wọn ní ẹ̀kọ́. Lára irú àwọn ẹ̀kọ́ bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀sìn ìbílẹ̀ tí ó wà ní àwùjọ wọn. Wọ́n tún máa ń kọ́ wọn ní èdè abínibi wọn. Wọn kì í sì í fi àwọn ẹ̀kọ́ àṣà ìbílẹ̀ wọn, iṣẹ́-ọnà àti oríṣìí àwọn ẹ̀kọ́ mìíràn

ṣeré. Wọn kì í gba àwọn ọmọdé láyè láti ronú lọ́nà òdì, kí wọ́n máà ba tàpá sí òfin àti èèwọ̀ inú àwùjọ wọn. Ó ní ṣe pẹ̀lú ọ̀nà tí wọ́n ń gbà jèrè ọkàn àwọn ọmọ náà lórí òfin, èèwọ̀, àṣà, ẹ̀sìn àti oríṣìí àwọn ìgbòkègbodò wọn mìíràn tí wọ́n fi ń ṣe ètò àwùjọ wọn. Ìdí nìyí, tí a fi gbàgbọ́ pé àṣà kì í kú bọ̀rọ̀. Nítorí pé, Òrìṣà tí a kò bá fi ìdí rẹ̀ han ọmọdé níí parun. Ọ̀nà tí àṣà àti ìṣe àwùjọ kì í sì í gbà parun ni àwọn Yorùbá tọ̀ láti máa fi lítíréṣọ̀ wọn kọ́ àwọn ọmọ wọn yìí.

Iṣẹ́ yìí yóò ṣe àfikún sí àwọn ìmọ̀ tó ti wà nílẹ̀ lórí lítíréṣọ̀ àwọn ọmọdé láwùjọ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. Iṣẹ́ yìí tún ṣe àfihàn bí àwọn agbègbè ìwádìí wa ti ń lo Òrìṣà Ẹgbẹ́ tí ó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn Òrìṣà Èwe láti fi kọ́ àwọn èwe wọn ní ìwà ọmọlúàbí, ẹ̀sìn, ìbára-ẹni-gbépọ̀, ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè, ìmọ̀-ìṣọwọ́lo-èdè àti ìmèdèélò, kí wọ́n má baà fi ojo pe Òjó. Bí àwọn ọmọdé sì ti ń dàgbà, ni òye àwọn ǹǹkan tí wọ́n ń kọ́ wọn yìí yóò máa yé wọn sí i. Èyí sì ni ohun tí wọn yóò máa fi ọkàn rò, tí wọn yóò sì máa fi ojú rí, tí wọn yóò máa fi etí gbọ́, tí wọn yóò máa fi ọwọ́ kàn, àti àwọn ohun tí wọn yóò máa ṣe akitiyan oríṣìíríṣìí lé lórí.

## Tíọ́rì Àmúlò fún Ìwádìí yìí

Tíọ́rì tí àwọn lámèétọ́ ìmọ̀ ìlò-àmì ṣẹ̀dá rẹ̀ nípa ṣíṣe àmúlò abala àwọn ìmọ̀ kan nínú àfojúsùn àwọn lámèétọ́ ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀ ni ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì. Tíọ́rì yìí ni a lò fún ìwádìí yìí. Àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí pọ̀, ṣùgbọ́n, a lo abala èyí tí ó jẹ mọ́ èrò Amber àti Haque (2004) tí ó ní ṣe pẹ̀lú àyẹ̀wò àwọn ẹ̀hun àwùjọ tí lítíréṣọ̀ máa ń pa àrokò rẹ̀.

### Ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì

Tíọ́rì méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí papọ̀ di ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì. Tíọ́rì àkọ́kọ́ ni ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-lítíréṣọ̀ tí àwọn agbátẹrù rẹ̀ gbàgbọ́ nínú àjọṣepọ̀ tó ń wáyé láàrin àwa ẹ̀dá àti ipa rẹ̀ lórí ìdàgbàsókè àwùjọ bí ó ti máa ń hàn nínú lítíréṣọ̀. Tíọ́rì kejì ni ìmọ̀-ìlò-àmì tí ó ní ṣe pẹ̀lú àrokò tí lítíréṣọ̀ pa lórí ìhun àwùjọ. Ohun tí ó mú díẹ̀ lára àwọn onímọ̀ ìlò-àmì gbìdánwò àkànpọ̀ tíọ́rì yìí àti ti àwọn onímọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀ ni pé, iṣẹ́ ìwádìí tiwọn jẹ mọ́ ìṣòro inú àwùjọ ju wíwo àmì ní ojú eréfèé. Wọ́n gbàgbọ́ pé, ọmọ iná là á rán síná ni ọ̀rọ̀ tíọ́rì ìbára-ẹni-gbépọ̀ Àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì pọ̀, ṣùgbọ́n, a lo abala èyí tí ó jẹ mọ́ èrò Amber àti Haque (2004).

Lára àwọn onímọ̀ tí wọ́n jẹ́ agbátẹrù fún tíọ́rì yìí ni Gergen, Keneth J. (1973), Kassin, Surfen àti Fein, Surfen (1978), Allport, G. W (1985), Sewell, W.H (1989), Triplett, Norman (1990), Walter, M. Geroson (1998), Amber àti Haque (2004) àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀ ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí níí ṣe àkànpọ̀ àwọn tíọ́rì méjèèjì yìí fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ àti àwọn ẹ̀yà iṣẹ́-ọnà mìíràn tí ó nípa pàtàkì lórí ìyanjú-ìṣòro àwùjọ. Èyí ni àwa náà gùn lé láti fi túmọ̀ àwọn kókó-èrò

ajẹmọ́-àwùjọ àwọn ọmọdé nínú àkóónú ìpohùn inú Ìbọ Èwe tí a fi ṣe àkójọ-èdè-fáyẹ̀wò láti ilẹ̀ Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú àti Yewa-Àwórì.

Amber àti Haque (2004) sọ ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ orírun tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì yìí àti àwọn agbátẹrù rẹ̀ tí wọ́n ti wá ìtúmọ̀ fún un. Níbẹ̀ ni a ti rí i kà pé, ilẹ̀ America ni wọ́n ti dá tíọ́rì yìí sílẹ̀ ní kété tí ogun Àgbáyé Ẹlẹ́ẹ̀kejì parí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àfijọ iṣẹ́ àwọn onímọ̀ tuntun yìí ti wà nínú ìwádìí àwọn onímọ̀ ìlò-àmì ti ìṣáájú, ọ̀nà-àrà tí àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí gan-an gbé e gbà ló pàálà sí ìlànà tí àwọn onímọ̀ ìṣáájú gbà lò ó gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ ìṣèwádìí wọn. Amber àti Haque (2004: 174) sọ pé:

> Although there were some old treatises about socio-semiotics, such as those by Islamic philosopher Al Farabi (Alpharabius), the discipline of socio-semiotics, as its modern-day definition, began in the United States of the dawn of the 20th century. …those in the emerging field of socio-semiotics were concerned with developing concrete explanations for different aspects of nature.
> (Lóòótọ́, àwọn ìgbésẹ̀ ìwádìí kan ti wáyé ṣáájú àwọn olùwádìí tuntun nípa ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì-lítíréṣọ̀, ní iṣẹ́ ìwádìí àwọn bíi onímọ̀-ìjìnlẹ̀-èrò ti Ìsìláàmù tí ń jẹ́ Al-farabi (Alpahrabius), ojúṣe ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì-lítíréṣọ̀, gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ mọ́ ìmọ̀ òde-òní, ó bẹ̀rẹ̀ láti ilẹ̀ United States ní ǹǹkan bíi ọ̀rúndún-gún…àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì tẹpẹlẹ mọ́ ìwádìí tó jinlẹ̀ nípa oríṣìí àbùdá-àdáni tí a mọ̀ mọ́ àwọn ẹ̀dá-alábùdá-àdáni.)

Àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí ní ìgbàgbọ́ nínú ìrírí àwọn ẹ̀dá ènìyàn nípa àmì àti àrokò nínú àwùjọ àti bí ìrírí náà ti ń kó ipa nínú ìrònú, ìṣesí, ìhùwàsí àti gbogbo ìgbòkègbodò wọn nínú ètò ìbára-ẹni-gbépọ̀. Wọ́n gbàgbọ́ pé, àwùjọ tí ènìyàn bá dàgbà sí ló máa ń hun ìwà tí ènìyàn yóò máa hù sílẹ̀ fún wọn. Fún ìdí èyí, tí àwọn ènìyàn bá ti ń hu ìwà tó yàtọ̀ sí ti inú àwùjọ rẹ̀, ó ṣeé ṣe kí ó jẹ́ pé ìrònú tirẹ̀ yàtọ̀ sí ti irúfẹ́ àwùjọ bẹ́ẹ̀. Bákan náà ni wọ́n gbà pé ìforíkorí àti ìfikùnlukùn àwọn ènìyàn nínú ìrònú wọn lè ràn wọ́n lọ́wọ́ láti lè yanjú ìṣòro inú àwùjọ wọn. Ohun tí ó ṣe pàtàkì jù lọ sí àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí, pàá pàá jù lọ, àwọn tí wọ́n ń lò ó fún àyẹ̀wò iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ ni pé, ìṣesí àti ìhùwàsí àwọn ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan lọ́tọ̀ọ̀tọ̀ nínú àwùjọ ló máa ń jẹ́ láàríjà iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀. Nítorí náà, lámèétọ́ tó bá ń lo tíọ́rì yìí fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀, ó gbọ́dọ̀ máa ṣe àkíyèsí àrokò inú àmì, èdè, èrò àwùjọ, ìhun àwùjọ, ìhùwàsí àwọn ènìyàn àti ojúṣe tí àwùjọ ń fẹ́ lọ́wọ́ wọn nínú àgbékalẹ̀ irúfẹ́ iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀.

### Ìdí tí a fi yan tíọ́rì yìí láàyò

Tíọ́rì yìí ni ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì, tí àfojúsùn àwọn agbátẹ̀rù rẹ̀ jẹ mọ́ wíwo ipa tí èrò-ọkàn àwọn ẹ̀dá ènìyàn lápapọ̀ ń kó nínú orísun àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ wọn gẹ́gẹ́ bí ó ti fara hàn nínú àgbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ wọn. Bákan náà ni tíọ́rì yìí ń tọ́ka sí àwọn ọ̀nà tí àwùjọ lè gbà lo àrokò inú lítíréṣọ̀ wọn láti yanjú ìṣòro ètò-ìbára-ẹni-gbépọ̀ inú àwùjọ wọn. Fún ìdí èyí, àwùjọ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí a ti ṣe ìwádìí wa jẹ́ àwọn àwùjọ tí kò ṣeé fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú àwùjọ Yorùbá lápapọ̀. Nítorí náà ni a ṣe wo ìlànà tí wọ́n ń gbà láti yanjú ìṣòro wọn nípa ṣíṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìpohùn inú Ìbọ Èwe tí wọ́n pè ní Ẹgbẹ́ Ọ̀gbà fún àwọn ọmọ wọn.

Ìgbàgbọ́ wa ni pé, àwọn kókó-èrò tó ṣú yọ nínú àkóónú àwọn ìpohùn inú Ìbọ Èwe ní ilẹ̀ Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú àti Yewa-Àwórì jẹ́ èyí tí wọ́n lò láti fi kọ́ àwọn ọmọ wọn ní òfin àti gbogbo àṣà, ẹ̀sìn pẹ̀lú ètò tó rọ̀ mọ́ ojú-àmúwayé wọn, kí àwọn ọmọ náà má baà ṣi ìwà hù nígbà tí wọ́n bá dé ipò àgbà nínú ètò-ìbára-ẹni-gbépọ̀ àwùjọ wọn. Nítorí náà, tíọ́rì yìí yóò wúlò fún ìwádìí yìí láti ṣe ìtúpalẹ̀ ajẹmọ́-tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo-ìlò-àmì fún àṣàyàn Òrìṣà Èwe láti mọ lááríjà rẹ̀ nínú ètò ìgbé ayé àwọn olùsìn rẹ̀ní ilẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú.

## Iṣẹ́ Onímọ̀ Ìṣáájú lórí Lítíréṣọ̀ Alohùn Ọmọdé

Lóòótọ́, Ìpohùn inú Ìbọ Èwe ló kàn wá nínú iṣẹ́ yìí, ṣùgbọ́n, a níláti tọ pinpin ojú tí àwọn onímọ̀ ìṣáájú fi wo ìpohùn inú Ìbọ Èwe nínú iṣẹ́ wọn. Lọ́nà àkọ́kọ́, a rí i pé kò lẹ́tọ̀ọ́ kí á máa pè é ní ìpohùn ọmọdé láìsọ irú abala ìpohùn ọmọdé tí à ń tọ́ka sí gan-an. Ìyẹn ni pé, oríṣìí ẹ̀yà ewì ọmọdé méjì ló wà. Ọ̀kan ni èyí tí wọ́n ṣẹ̀dá fún wọn, tó sì jẹ́ ìpohùn nìkan, tí ìkejì sì jẹ́ ewì ọmọdé tí wọ́n ṣẹ̀dá fún wọn láti máa kà nínú ìwé. Fún ìdí èyí, abẹ́ lítíréṣọ̀ ọmọdé ni àwọn ìsọ̀rí ewì ọmọdé méjèèjì wà. Lára àwọn onímọ̀ tí wọ́n ti ṣe iṣẹ́ lórí lítíréṣọ̀ ọmọdé ni Dáramọ́lá àti Jéjé (1967), Finnegan (1970), Àrẹ̀mú (1974), Abọ́dúndé (1975), Adéoyè (1979), Oyèwùsì (1980), Ọlátúnjí (1984), àti Owólabí (1985)

Ìwádìí Finnegan (1970) dá lórí lítíréṣọ̀ alohùn ilẹ̀ Adúláwọ̀ lápapọ̀. Nínú ìwádìí tí ó ṣe náà ló ti ṣe àfihàn èrò rẹ̀ nípa lítíréṣọ̀ tó wà fún àwọn ọmọdé láwùjọ Adúláwọ̀. Ó tọ́ka sí àlọ́ pípa (àpamọ̀ àti àpagbè) gẹ́gẹ́ bí ilé-ìṣúra ọgbọ́n nínú àwùjọ Adúláwọ̀ lápapọ̀. Bákan náà ló wòye onírúurú orin eré ìdárayá tí àwọn ọmọdé máa ń kọ. Ó fi yé wa pé orin eré ìdárayá kún fún ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí ní ilẹ̀ Adúláwọ̀. Finnegan (1970: 299-303) sọ nínú àkíyèsí rẹ̀ pé:

> Litle systematic interest has been taken in childrens' verse in Africa… Like children elsewhere, African children seen to have the familiar range of games and verse for their own playsinging songs, singing games, catch

rhymes and so on. They also engaged in riddle asking and in other games and dances.

(Ìwádìí péréte ni àwọn ènìyàn ṣì ṣe lórí ìpohùn ọmọdé ní ilẹ̀ Adúláwọ̀… Gẹ́gẹ́ bí àwọn ọmọdé ní ilẹ̀ ibòmíràn, àwọn ọmọdé ní ilẹ̀ Adúláwọ̀ ní àwọn oríṣìíríṣìí orin àti àwọn ewì fún eré wọn, àwọn orin kíkọ, àwọn orin eré, orin kíkọ lọ́wọ̀ọ̀wọ́, tó bá eré mu àti oríṣìí àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. Bákan náà ni wọ́n tún máa ń kópa nínú àlọ́ àpamọ̀, oríṣìí eré mìíran pẹ̀lu ijó jíjó.)

Onímọ̀ yìí fi ìdí ọ̀rọ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé, oríṣìí àwọn lítíréṣọ̀ alohùn tó wà fún àwọn ọmọdé lè wáyé ní ìlànà eré-oníṣe, ewì tàbí àwọn ìlànà mìíràn. Ó fi yé wa pé ijó jíjó àti ìlù pẹ̀lú oríṣìí àwọn eré ìdárayá mìíràn tún wà tí àwọn ọmọdé máa ń ṣe. Ohun tí ó ṣe pàtàkì ni pé, Finnegan (1970:299-303) gbà pé àwọn ọmọdé náà ní lítíréṣọ̀ alohùn tiwọn. Finnegan (1970:299-303) kò ṣe ìpínsísọ̀rí lítíréṣọ̀ ọmọdé, ṣùgbọ́n, a rí i pé ti alohùn nìkan ni ìwádìí rẹ̀ dá lé. Ó tọ́ka sí orin tí ó jẹ́ ewì alohùn àti eré-oníṣe tí ó pè ní (*game*)[2] láti fi hàn pé ọ̀kan lára lítíréṣọ̀ alohùn àwọn ọmọdé ni.

Nínú ìwádìí Dáramọ́lá àti Jéjé (1967), gbogbo ohun tó gbé àṣà àti ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá dúró ni wọ́n ṣe ìwádìí wọn lé lórí. Èyí ló mú wọn ṣe àfihàn onírúurú eré ìdárayá tó wà fún àwọn ọmọdé láwùjọ Yorùbá. Àwọn onímọ̀ yìí kò ṣe àfihàn pé ewì kíké ni òpómúléró fún àwọn eré ìdárayé náà. Lójú Dáramọ́lá àti Jéjé (1967), orin kíkọ, òkòtó títa, ìsọ̀rọ̀kéwì, àti gbogbo àwọn n̄ǹkan mìíràn tó rọ̀ mọ́ lítíréṣọ̀ ọmọdé nílẹ̀ Yorùbá já sí eré ìdárayá. Ìwádìí tiwa fi hàn pé lítíréṣọ̀ alohùn ni gbogbo àwọn akitiyan náà já sí, kì í ṣe eré ọmọdé lásán. A fi ìdí èyí múlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ wa lórí lítíréṣọ̀ alohùn. Lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́ ìlànà ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́, ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́, ìdánilárayá, àti ìtọ́nisọ́nà lórí àṣà àwùjọ wa. Gbogbo àwọn àbùdá yìí ló sì hàn nínú akitiyan àwọn ọmọdé tí a pè ní lítíréṣọ̀ alohùn wọn yìí.

Láti fi hàn pé kì í ṣe gbogbo Ìpohùn inú Ìbọ Èwe ni ó jẹ́ eré ìdárayá, a níláti mọ̀ pé àwọn ewì alohùn kan wà tí ó jẹ mọ́ ẹ̀sìn[3], ẹ̀kọ́ nípa etò-ìṣèlú àti ètò-ọrọ̀-ajé pẹ̀lú ìbára-ẹni-gbépọ̀. Bákan náà ni wọ́n nípa lórí ètò-mọ̀lẹ́bí, ẹ̀bùn sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀ àti àwọn ètò mìíràn láwùjọ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ́bú. Wọ́n tún ní àwọn ewì alohùn tí ó wà fún àwọn ọmọdé láti kọ́ wọn ní ètò-ìlera àti ìgbádùn. Fún ìdí èyí, àwọn ìṣẹ̀ré tí Dáramọ́lá àti Jéjé (1967:8) tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí eré ìdárayá ní ilẹ̀ Yorùbá jẹ́ abala kan nínú àwọn lítíréṣọ̀ alohùn ọmọdé. Dáramọ́lá àti Jéjé (1967:8) tilẹ̀ sọ pé:

Ó jẹ́ àṣà jákè jádò ilẹ̀ Yorùbá pé nígbà tí ọwọ́ bá di'lẹ̀ nwọn yóò ma wá nkan f'ọwọ́ pa tàbí láti ma a fi dárayá… Bí a bá sì tún f'etí sí àwọn àgbàgbà nígbàmíràn, a ó gbọ tí wọ́n ńsọ bayi pé "Tọmọdé t'tàgbà ní íyọ̀ mọ́ ọmọ ayò". Èyí tún fi hàn kedere pé kò sí ẹni tí kì í ta ayò… Bí eré ayò ti ṣe pàtàkì fún ìdárayá bẹ́ẹ̀ ni eré àrín ṣe pàtàkì pẹ̀lú.

Ohun tí a fẹ́ fàyọ nínú àyọlò àwọn onímọ̀ yìí ni pé, wọ́n gbà pé àṣà Yorùbá ni ìdárayá ṣíṣe jẹ́, ó sì jẹ mọ́ akitiyan àkókò tí ọwọ́ bá dìlẹ̀. Fún ìdí èyí, àwọn lítíréṣọ̀ alohùn ọmọdé tí ó jẹ mọ́ ìdárayá nìkan ni wọ́n lè wáyé ní àkókò tí ọwọ́ bá dilẹ̀. Lára irú àwọn lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ ni àlọ́ pípa, bojú boojú àti onírúurú àwọn eré òṣùpá mìíràn. Ṣùgbọ́n, àwọn lítíréṣọ̀ alohùn ọmọdé tí ó jẹ mọ́ ẹ̀sìn kò ṣeé fi ojú erémọdé lásán wò nínú àwùjọ Yorùbá lápapọ̀. Àpẹẹrẹ irú wọn ni orin Àgàṣa fún Òrìṣà èwe àti orin Òrìṣà kórì tí ó jẹ́ Òrìṣà èwe bákan náà ní ilẹ̀ Ẹ̀gbá àti Yewa-Àwórì.

Àrẹ̀mú (1974) náà ṣe ìwádìí lórí àwọn eré ọmọdé tó jẹ mọ́ oúnjẹ, ọ̀gbìn, ẹyẹ àti àmúlò àwọn ohun àyíká. Onímọ̀ yìí náà kò fi ojú lítíréṣọ̀ wo eré ọmọdé láwùjọ Yorùbá. Lójú rẹ̀, eré ni àwọn ọmọdé ń fi àwọn ẹ̀ya ewì alohùn bí orin kíkọ àti ìmọ́ bíbú ṣe. Tí a bá sì wo àkíyèsí rẹ̀ nípa àwọn ohun àyíká tó ń tọ́ka sí nínú ìpohùn ọmọdé tó fi hàn nínú ìwádìí rẹ̀, a ó rí i pé, èròǹgbà àwọn Yorùbá láti máa fi àwọn ohun àyíká kọ́ àwọn ọmọ wọn ló bí irú àwọn ewì alohùn bẹ́ẹ̀.

Bákan náà ni Abọ́dúndé (1975) ṣe ìwádìí lórí àlọ́ gẹ́gẹ́ bí eré òṣùpá tí ó wà fún àwọn ọmọdé. Ó fi hàn nínú èrò rẹ̀ pé "…àlọ́ jẹ́ ọ̀kan nínu àwọn ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà kọ́ ọmọ wọn lẹ́kọ̀ọ́ kí àwọn Òyìnbó tó kó ẹ̀kọ́ ìwé dé àwùjọ Yorùbá". Ó ṣàlàyé sí i nínú ìwádìí rẹ̀ yìí pé, irúfẹ́ ẹ̀kọ́ tí àwọn Yorùbá bá fẹ́ kọ́ àwọn ọmọ wọn, ló máa ń ṣe okùnfà àlọ́ tí wọn yóò gbé kalẹ̀ fún wọn. A gbà pé lóòótọ́, àwọn ọmọdé ni wọ́n ń pa àlọ́ fún, ṣùgbọ́n, ẹ̀kọ́ inú àlọ́ tayọ ti àwọn ọmọdé nìkan. Àlọ́ àpamọ̀ àti àlọ́ àpagbè kún fún ẹ̀kọ́ tí àwọn àgbàgbà náà lè kọ́ níbẹ̀. Àlọ̀ tí onímọ̀ yìí ṣe ìwádìí lé lórí jẹ́ ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí wọ́n gbé kalẹ̀ fún àwọn ọmọdé. Lójú tirẹ̀, àpèjúwe tí ó lè ṣe nípa àlọ́ tí ó jẹ́ ẹ̀yà kan nínú lítíréṣọ̀ àwọn ọmọdé yìí ni ìlànà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú àwùjọ Yorùbá. Àpèjúwe onímọ̀ yìí sì tọ̀nà nípa ìwádìí tí a ṣe lórí lítíréṣọ̀ ọmọdé èyíkéyìí yòówù kó jẹ́, ẹ̀kọ́ ni àwọn Yorùbá ń lò wọ́n láti fi kọ́ àwọn ọmọ wọn.

Adéoyè (1979) fi ìwádìí tirẹ̀ lórí àwọn àṣà inú àwujọ Yorùbá tan ìmọ́lẹ̀ sí onírúurú àṣà àti ìṣe tó gbé àwùjọ Yorùbá ró. Èyí ló mú kí Adéoyè (1979: 55-80) tọ́ka sí àwọn lítíréṣọ̀ ọmọdé gẹ́gẹ́ bí eré ìdárayá ilẹ̀ Yorùbá. Onímọ̀ yìí gbà pé ètò-ẹ̀kọ́ tí ó wà láwùjọ Yorùbá ṣáájú ìmọ̀-mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà ni àwọn erémọdé náà jẹ́. Erémọdé ni onímọ̀ yìí pe àwọn lítíréṣọ̀ alohùn ọmọdé láwùjọ Yorùbá lápapọ̀. Adéoyè (1979: 55-80) sọ pé: "Lẹ́hìn tí ọmọ ti bẹ̀rẹ̀ sí kọ́ erémọdé, kò sí ọ̀nà tí ó mú ìrọ̀rùn wà fún ọmọ ju kí á fi ijó àti orin kọ́ ọmọ náà ní ǹǹkan kíkà lọ." Àyọlò yìí fi hàn pé ìlànà tí ó jẹ mọ́ ewì alohùn àti eré-oníṣe nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni erémọdé jẹ́. Onímọ̀ yìí fi èrò rẹ̀ pe àkíyèsí wa sí ìlànà ètò-ẹ̀kọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá, gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti ní ìpele kọ̀ọ̀kan fún ẹ̀kọ́ tí ó yẹ fún àwọn ọmọdé lọ́tọ̀ọ̀tọ̀ láìṣe àfibọ̀ fún wọn. Nínú àyọlò òkè yìí, ijó àti orin tí onímọ̀ yìí tọ́ka sí fi hàn pé ewì alohùn ló wà lọ́kàn rẹ̀, tí ó pè ní erémọdé. Ọ̀kan lára àwọn ẹ̀ya lítíréṣọ̀ alohùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta sì ni ewì jẹ́. Inú ewì alohùn ni a ti rí àpẹẹrẹ orin kíkọ.

Oyèwùsì (1980) náà ṣe ìwádìí nípa lítíréṣọ̀ alohùn ọmọdé. Ogójì eré òṣùpá ni òun ṣe àkójọ rẹ̀ sínú ìwé rẹ̀. Onímọ̀ yìí náà kò ní lítíréṣọ̀ lọ́kàn nínú iṣẹ́ rẹ̀ yìí, àṣà àwùjọ Yorùbá ló ka àwọn ogójì eré òṣupá náà sí. Ó pín àwọn eré òṣùpá náà sí ìsọ̀rí méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ó pe àwọn ìsọ̀rí àkọ́kọ́ ní eré ìdárayá pọ́ńbélé, ó sì pe àwọn ìsọ̀rí kejì ní eré òṣùpá oníjó-lórin. Ìsọ̀rí kejì rẹ̀ yìí gan-an ló fi hàn pé Ìpohùn inú Ìbọ Èwe ló ní lọ́kàn, tí àwọn ti ìsọ̀rí àkọ́kọ́ sì jẹ mọ́ eré-oníṣe.

Onímọ̀ àkọ́kọ́ tí ó kọ́kọ́ tọ́ka sí erémọdé àwùjọ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí lítíréṣọ̀ alohùn ni Ọlátúnjí (1984). Àlọ́ àpamọ̀ tó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ewì alohùn tó wà fún ọmọdé ni onímọ̀ yìí fi hàn nínú ìwádìí rẹ̀. Èyí ló ṣe okùnfà àlàyé tí ó ṣe nípa àwọn ẹ̀yà eré òṣùpá mìíràn tí àwùjọ Yorùbá gbé kalẹ̀ ní ìlànà lítíréṣọ̀ alohùn. Ó rí àlọ́ àpagbè gẹ́gẹ́ bí èyí tó ní àbùdá eré-oníṣe nínú ìhun rẹ̀. Ó tún gbà pé onírúurú àwọn ewì alohùn bí àrọ̀ jíjá, ìmọ́ bíbú àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀ náà máa ń wáyé ní ìlànà eré-oníṣe. Ó fi yé wa pé, àwọn kan lè wáyé ní ìlànà orin, kí àwọn mìíràn sì tún wáyé ní ìlànà ìsọ̀rọ̀kéwì. Ọlátúnjí (1984:181) pe àkíyèsí wa sí iṣẹ́ tí àwọn onímọ̀ ìṣáájú bí Túgbìyèlé (1948), Abraham (1958), Bascom (1949) àti Májàsán (1967) ṣe lórí àlọ́ pé gbogbo wọn kò ṣe àfihàn àlọ́ gẹ́gẹ́ bí ara lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Ọlátúnjí (1984:181) sọ pé:

> Ulli Beier (1959, P.58) mentions them in a paragraph in his book but then, he considers them to be 'poetry for children'. But when he says 'children and grown-ups vie with each other in giving poetic descriptions of the objects to be gnessed. Many of them show indeed a true sense of poetic vision' (p.58), one wonders why, in spite of this mutual general participation, Ulli Beier still regards àlọ́ àpamọ̀ as poetry for children.
> (Ulli Beier (1959, o.i.58) tọ́ka sí wọn nínú ìpínrọ̀ kan nínú ìwé rẹ̀, síbẹ̀ náà, "ewì ọmọdé" ni ó pè wọ́n. Ṣùgbọ́n, nígbà tí ó tún wá sọ pé 'àwọn ọmọdé àti àwọn àgbàgbà máa ń jọ ṣe papọ̀ láti ṣe àgbékalẹ̀ ewì tí wọ́n fi ń hun àlọ́ àpamọ̀. Ọ̀pọ̀ nínú wọn ló jẹ́ ewì pọ́ńńbélé" (o.i 58), ó wá ya ni lẹ́nu pé, pẹ̀lú gbogbo àjọṣepọ̀ gbogbogbòò nínú àlọ́ àpamọ̀, Ulli Beier ṣì tún ń pè é ní ewì ọmọdé)

Lóòótọ́ ni pé, àwọn àgbàgbà a máa kópa nínú àlọ́, gẹ́gẹ́ bí Ọlátúnjí (1984:182) ti sọ nínú àyọlò òkè yìí, ṣùgbọ́n, a rí i pé èrò Ulli Beier (1959:58) tọ̀nà pé ìpohùn ọmọdé ni àlọ́ àpamọ̀ jẹ́. Ìdí ni pé, àwọn ọmọdé gan-an ni àfojúsùn àwùjọ Yorùbá lórí lááríjà àlọ́ pípa. Àwọn àgbàágbà máa ń kópa nínú àgbékalẹ̀ àlọ́ pípa fún àwọn ọmọdé láti lè máa túmọ̀ àlọ́ náà fún wọn.

Iṣẹ́ tí Owólabí, Olúnládé, Adéràntí àti Ọlábimtán (1985: 85) ṣe lórí lítíréṣọ̀ alohùn ọmọdé náà fi hàn pé abala ewì ló jẹ wọ́n lógún. Níṣe ni wọ́n tilẹ̀ là á mọ́lẹ̀ nínú ìwádìí wọn pé ewì alohùn ni àwọn ọmọdé ń ké nínú eré ìdárayá wọn. Owólabí, Olúnládé, Adéràntí àti Ọlábimtán (1985: 85) sọ pé "Ìpohùn ọmọdé wà ní oríṣiríṣi. Iṣẹ́ tí wọ́n ń fi oríṣi kọ̀ọ̀kan ṣe sì yàtọ̀. Àwọn ewì kan wà

tí àwọn ìyá ọmọ fi ń rẹ ọmọ wọn lẹ́kún… Àwọn ewì mìíràn sì wà tí ó jẹ́ àwọn ọmọdé fúnra wọn ni ó máa ń lò ó”. Àwọn onímọ̀ yìí gbà pé ọ̀kan lára àwọn lítíréṣọ̀ ọmọdé ni orin ìrẹmọlẹ́kún jẹ́, ní èyí tí ìwádìí fi hàn wá gẹ́gẹ́ bí ewì tí àwọn ìyá ọmọ ń ké fún ọmọ wọn. Ṣùgbọ́n, ní ti àwọn àpẹẹrẹ bí Ẹyẹ mẹ́ta tolongo wáyé, Ení bí ení, Mọ̀-ọ́n, Kí ní hewú? àti Kóórì tí wọ́n tọ́ka sí nínú ìwádìí wọn yìí, a gbà pé Ìpohùn inú Ìbọ Èwe ni gbogbo wọn. Orin ìrẹmọlẹ́kún kì í ṣe ewì alohùn ọmọdé.

## Ipa àti Ipò Àwọn Ọmọdé nínú Ìbọ Èwe ní Agbègbé Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú

## Aṣògún Ọmọọlé (Abọrẹ̀)

Àwọn ọ̀dọ́ tí wọ́n jẹ́ ọmọ agboolé tí wọ́n ti ń sin Òrìṣà Ògún àti Egúngún ni oyè Olórí wọn jẹ́ Aṣògún Ọmọọlé, òun sì ni Abọrẹ̀ fún àwọn èwe ní àkókò àjọ̀dún wọn. Àwọn Ọ̀jẹ̀ wẹ́wẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bí akópa pàtàkì nínú àwọn ọdún Òrìṣà Èwe ní ìlú Ọ̀tà Àwórì àti àwọn ìlú mìíràn ní ilẹ̀ Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú máa ń ṣe onírúurú akitiyan nínú ọdún Egúngún àti ìbọ àwọn Òrìṣà Èwe yòókù, pàápàá, lásìkò tí àwọn Eégún ọ̀dọ́ bá jáde. Akitiyan wọn pọ̀ lásìko ọdún Eégún. Ní pàtàkì àwọn ni wọ́n máa ń mú ọdún Egúngún dùn. Lára ohun tí wọ́n máa ń gbé ṣe ni ẹ̀ṣà pípè, ẹ̀kú Eégún rírù, fífọ ẹ̀kú Eégún ní odò, ijó jíjó àti òkìtì títa. Àwọn ọ̀dọ́ yìí ni wọ́n máa ń díje ijó jíjó, orin kíkọ àti ẹ̀ṣà pípè. Ọ̀pọ̀ nínú Egúngún wọn ló máa ń jẹ́ aláwàdà tí ń ṣe ìsínjẹ fún àwọn ìwà ìbàjẹ́ àwùjọ wọn. Àpẹẹrẹ irú àwọn Eégún tí a rí ní ìlú Ọ̀tà Àwórì ni: Àkóbá Ìdìrè, Tóńtobẹ̀, Ìdíìlẹ̀kẹ̀, Orí-Àrán, Fọ́kòkò, Fọ́pomọ́yọ̀, Ṣáaláàáké, Gbájúẹ̀, Májowú-ọkọ, Ọmọ-Àlè àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀.

Lọ́pọ̀ ìgbà, àwọn ọ̀jẹ̀wẹ́wẹ́ ni wọ́n máa ń ṣe ìsínjẹ fún ìwà jàjídíjàgan tí ń wáyé láàrin àwùjọ wọn. Bákan náà ni wọ́n máa ń dá orin ọ̀tẹ́ àti èébú láàrin ìlú. Àpẹẹrẹ kan nìyí:

Ohùn ÌIù: Dìgbò lù ú
Kọ lù ú
Dìgbò lù ú
Kọ lù ú
Lílé: Bẹ́ẹ̀ bá rọ́mọ ọ̀bọ
Tó ń perúu wa
Lákẹ́bọjẹ
Tó ń perúu wa
Lábọ̀rìṣàà
Bó bá rín wa fín-ín
Bó bá rín wa fín-ín
Ẹ má baa jà

Ẹ já wọn ní patiyẹ
Kó gbórìṣà relé
Kò ní ṣeerú ẹ̀ mọ́ o
Ègbè: Bẹ́ẹ̀ bá rọ́mọ ọ̀bọ
Tó ń perúu wa
Lákẹ́bọjẹ
Tó ń perúu wa
Lábọ̀rìṣàà
Bó bá rín wa fín-ín
Bó bá rín wa fín-ín
Ẹ má baa jà
Ẹ já wọn ní patiyẹ
Kó gbórìṣà relé
Kò ní ṣeerú ẹ̀ mọ́ o

Orin ọ̀tẹ̀ gbáà ni àyọlò òkè yìí. Bí a bá wo gbólóhùn tó wà ní ìlà kọkànlá sí ìlà kẹrìndínlógún àyọlò òkè yìí, ó hàn kedere pé àwọn ọ̀tá wọn ni wọ́n ń bá wí. Ó ṣéèṣe kí ó jẹ́ àwọn ẹlẹ́sìn ìgbàlódé tí wọn máa ń bu ẹnu àtẹ́ lu ẹ̀sìn ìbílẹ̀ pé ẹ̀ṣìn tí kò dára ni wọ́n ń bá wí. Nínú àyọlò náà, patiyẹ tí wọ́n sọ pé àwọn yóò kó yá ẹni tó pe àwọn ní akẹ́bọjẹ tọ́ka sí àwọn ẹgba ẹ̀rẹ̀ tí wọ́n ti rẹ ní oògùn. Ẹni tí wọ́n bá fi ẹgba ẹ̀rẹ̀ náà nà, àìsàn yóò kọ lù ú. Èyí ni wọ́n fi lo ìpèdè "Kó gbórìṣà relé" tó wà nínú àyọlò náà.

## Olórí Èré àti Àwọn Ẹgbẹ́ Èwe mìíràn (Àwòrò)

Olórí Èré ló jẹ́ oyè pàtàkì nínú Ẹgbẹ́ Èwe ní ilẹ̀ Yewa-Àwórì àti Ẹ̀gbá. Ipa tí Olórí Èré ń kó nínú akitiyan àwọn ọ̀dọ́ nígbà tí àjọ̀dún Èwe èyíkéyìí bá wáyé ní ilẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú kò kéré. Nínú àjọ̀dún Òrìṣà Ẹgbẹ́ Ọ̀gbà ní ilẹ̀Ẹ̀gbá, Olórí Èré ló ń kó ipa gẹ́gẹ́ bí Àwòrò. Bákan náà ẹ̀wẹ̀, àwọn ọmọdé mìíràn ń kó ipa gẹ́gẹ́ bí Àwòrò nínú àjọ̀dún Òrìṣà Èwe bí Láráagbó, Kórìkóto, YemulẹÌjẹ̀bú àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. Àjọṣepọ̀ tó mọ́yan lórí wà láàrin gbogbo àwọn Ẹgbẹ́ Olórìṣà ilẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. Àwọn ẹgbẹ́ mẹ́rin ni wọ́n ràn wá lọ́wọ́ nínú ìwádìí yìí ní agbègbè mẹ́tẹ̀ẹ̀ta.

Ìwádìí fi hàn wá pé, kò fẹ́ẹ̀ sí ìyàtọ̀ tàbí ààlà ìbáṣepọ̀ láàrin gbogbo àwọn ẹgbẹ́ náà láti Yewa-Àwórì títí dé Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú lápapọ̀. Èyí gan-an tilẹ̀ mú ìwádìí rọrùn fún wa, níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé, bí a ti ń dé ọ̀dọ̀ àwọn kan nínú àwọn ẹgbẹ́ Òrìṣà ìbílẹ̀ wọ̀nyí, ni wọ́n ń mú wa lọ sí ibòmíràn tí àwọn ẹgbẹ́ wọn wà. A tilẹ̀ rí omidan kan nínú wọn tí ó jẹ́ akópa nínú mẹ́ta pàtàkì nínú àwọn Òrìṣà Èwe náà. Omidan yìí jẹ́ Olórí Èré fún gbogbo àwọn Òrìṣà Èwe mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tó ń

sìn. Ó sì tún wà nínú Ẹgbẹ́ Èwe mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ wọ̀nyí ní Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú:

1. Ìmọ́lẹ̀ Omi
2. Atikékerémojú-ewé
3. Alárágbó Ìṣẹ̀ṣelàgbà àti
4. Ìṣẹ̀ṣe Congress (Àwọn Ọ̀dọ́)

Ohun tí èyí tọ́ka sí ni pé, ẹ̀sìn ìbílẹ̀ àwọn Èwe ní ilẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú fara hàn nínú ètò ìbára-ẹni-gbépọ̀ wọn, gẹ́gẹ́ bí àmì kan pàtàkì nínú àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀sìn náà.

## Ìfèdèpàrokò nínú Ìbọ Ẹgbẹ́ Ọ̀gbà ní agbègbè Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú

Abala àwọn ewì alohùn, pàápàá orin àjọ̀dún àti àwọn ewì alohùn mìíràn tó ṣú yọ nínú àgbékalẹ̀ Ìbọ àwọn Òrìṣà Èwe tí a yàn láàyò ni a ó dojú kọ níbí. Àwọn ìlò-èdè tó jẹ mọ́ Ìwúre, Oríkì, Òwe àti Ẹ̀fẹ̀ ni a ó wo lááríjà wọn lábẹ́ ìsọ̀rí yìí. Ohun tó jẹ wá lógún gan-an ni ìtúpalẹ̀ àrokò tí àwọn olùsìn àwọn Òrìṣà Èwe yìí ń fi àwọn afọ̀ náà pa nínú àgbékalẹ̀ wọn.

### Èdè Ìjúbà

Onírúurú àǹfààní tó wà nínú ìbà jíjú ló máa ń mú àwọn akéwì alohùn Yorùbá fi ìjúbà ṣí de eré tí wọ́n bá fẹ́ ṣe. Yàtọ̀ sí ìjúbà tó máa ń wáyé ní ìbẹ̀rẹ̀ eré, wọ́n tún máa ń ṣe àmúlò ìbà jíjú láàrin ìhun eré tàbí ní òpin eré tí wọ́n bá ń ṣe. Ṣùgbọ́n, ìwádìí fi hàn wá wí pé ìjúbà tó máa ń wáyé ní ìbẹ̀rẹ̀ eré ló jẹ àwọn apohùn lógún lọ́pọ̀lọpọ̀. Ọlájubù (1972:7) sọ pé:

> Nísisiyìí ẹ jẹ́ kí á wá yiri iwì gan-an wò. Gẹ́gẹ́ bí àwọn akéwì àtẹnudẹ́nu yòókù ní ilè wa, ibi ìbà ni akíwì egúngún ti máa ń bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ rẹ̀. Ìgbàgbọ́ àwa Yorùbá ni pé bí ènìyàn bá dáwọ́lé eré kan tàbí ohunkóhun láìjúbà àwọn tí óso ilé ayé àti òde ọ̀run ró, eré náà tàbí ohunkóhun bẹ́ẹ̀ kò ní yọ rí sí rere. Àwọn wo ni akíwì í máa juba? Wọn a máa juba Ọlọ́run tàbí 'ọlọ́jọ́ òní', Èṣù, àwọn àjẹ́, àwọn aṣáájú wọn níbi eré, baba àti ìyá tí ó bí wọn, àwọn òrìṣà gbogbo, àní wọn a máa júbà gbogbo agbára tí wọ́n bá rántí, àti gbogbo ènìyàn lápapọ̀.

Onímọ̀ yìí túṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò lórí ìtumọ̀ àti lááríjà ìbà jíjú láwùjọ Yorùbá àti fún àwọn akéwì alohùn lápapọ̀. Ọlájubù (1972) tan ìmọ́lẹ̀ sí irúfẹ́ àwọn ẹ̀dá tí àwọn akéwì alohùn máa ń júbà wọn ṣáájú eré tí wọ́n bá fẹ́ ṣe, ó sì tọ́ka àtúnbọ̀tán tó wà fún akéwì tí kò bá júbà ṣáájú eré rẹ̀. Bákan náà ló tún sọ ọ́ dí

mímọ̀ wi pé ìgbàgbọ́ Yorùbá ló rọ̀ mọ́ ìbà jíjú àti pé ó kọjá ọ̀rọ̀ àṣà àti ìṣe lásán. Àpẹẹrẹ afọ̀ ìjúbà kan nìyí láti inú orin Kórìkóto:

| | |
|---|---|
| Lílé: | Kábíesí Rẹ, |
| | Ééledùmárè |
| | Tóótó, |
| | Mọ pè júbà ooo |
| | Mọ ṣe ìbà Aadáalìwááyé ò ò |
| | Mọ̀ ti ṣidé, |
| | Á a aaa |
| | Àwòrò eré yáá |
| | Ẹ gbá wa mú, |
| | Ọ́ yáá |
| Ègbè: | A ṣèbà Akọ́dáá |
| | A ṣèbà Aṣẹ̀dáá |
| | A ṣe ìbà Ẹ Adáaliwáyé òòò |
| | A ti ṣídee, |
| | Á aaaa |
| | Àwòrò |
| | Eré yáá |
| | Ẹ gbá wa mú, |
| | Ọ́ yáá |
| Lílé: | A ti ṣíde lónìí, |
| | Elédùmarè |
| | Ẹ sinni lọọọ |
| Ègbè: | Akọ́dá Àgbááyeè |
| | Eré yá mi òòò |
| | Kí n tẹ́gbẹ́ láyéé |
| Lílé: | Abiyamú kọ̀ jẹ́ẹ́ gbàgbé ọmu rẹ̀ ooo |
| Ègbè: | Bàbá má gbàgbé mi |
| | Kí n tẹ́gbẹ́ láyéé |
| Lílé: | A ti ṣíde lónìí |
| | A pElédùmarè |
| | Kẹ sinni lọọọ |
| Ègbè: | Akọ́dá Agbááye |
| | Eré yá mi òòò |
| | Kí n tẹ́gbẹ́ láyéé |
| Lílé: | Abiyamu kọ̀ jẹ́ẹ́ gbàgbé ọmu rẹ̀ ooo |
| Ègbè: | Bàbá má gbaagbé miii |
| | Kí n tẹ́gbẹ́ láyéé |
| Lílé: | Ìkọ̀ọ̀tún, |

| | |
|---|---|
| | Mọ pè júúbà ooo |
| Ègbè: | Èéé, |
| | A júbà i yín o òòò |
| | Kẹ jẹ́ kéré yẹ wáá |
| Lílé: | Ìkọ̀tún a pè júúbà ooo |
| Ègbè: | Ẹẹ̣ẹ, |
| | Ìkọ̀tún Eléṣuuṣùù |
| | Mo pè yín |
| | Ọ́ yáá |
| (Lílé: | Kábíesí Rẹ, |
| | Ééledùmárè |
| | Tóótó, |
| | Mo pè júbà ooo |
| | Mo ṣe ìbà Aadáaniwááyé ò ò |
| | Mo ti ṣidé, |
| | Á a aaa |
| | Àwòrò |
| | Eré yáá |
| | Ẹ gbá wa mú, |
| | Ó yáá |
| Ègbè: | A ṣèbà Akọ́dáá |
| | A ṣèbà Aṣẹ̀dáá |
| | A ṣe ìbà Ẹ Adáaniwáyé òòò |
| | A ti ṣídee, |
| | Á aaaa |
| | Àwòrò |
| | Eré yáá |
| | Ẹ gbá wa mú, |
| | Ó yáá |
| Lílé: | A ti ṣíde lónìí, |
| | Elédùmarè |
| | Ẹ sinni lọọ̣ |
| Ègbè: | Akọ́dá Àgbááyeè |
| | Eré yá mi òòò |
| | Kí n tẹ̣gbẹ́ láyéé |
| Lílé: | Abiyamọ kò jẹ́ẹ́ gbàgbé ọmọ rẹ̀ ooo |
| Ègbè: | Bàbá má gbàgbé mi |
| | Kí n tẹ̣gbẹ́ láyéé |
| Lílé: | A ti ṣíde lónìí |
| | A pElédùmarè |
| | Kẹ sinni lọọ̣ |

Ègbè: Akọ́dá Agbááyé
Eré yá mi òòò
Kí n tẹ́gbẹ́ láyéé
Lílé: Abiyamọ kò jẹ́ẹ́ gbàgbé ọmọ rẹ̀ ooo
Ègbè: Bàbá má gbaagbé miii
Kí n tẹ́gbẹ́ láyéé
Lílé: Ìkọ̀ọ̀tún,
Mo mà júúbà ooo
Ègbè: Èéé,
A júbàa yín o òòò
Kẹ́ẹ jẹ́ kéré yẹ wáá
Lílé: Ìkọ̀tún a mà júúbà ooo
Ègbè: Ẹẹẹ,
Ìkọ̀tún Eléṣuuṣùù
Mo pè yín
Ó yáá)

Nínú àyọlò tó wà lókè yìí, a rí i pé Ọlọ́run ni apohùn yìí kọ́kọ́ fi ṣíwájú nínú ìbà tó ń jú. Èyí fi hàn wí pé ojú-àmúwayé àwọn Yewa-Àwórì nípa ipò tí Ọlọ́run wà sí àwa ẹ̀dá èniyàn ló fara hàn nínú àgbékalẹ̀ ìpohùn yìí. Bí ọ̀rọ̀ ìbà jíjú ti ṣe pàtàkì nínú ìgbé ayé àwọn Yorùbá, ni wọ́n fi mú ìjúbà ní ọ̀kúnkúndùn nínú ìpohùn tó jẹ mọ́ ìbọ Òrìṣà Èwe láwùjọ wọn. Èyí fi hàn pé, àwọn Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú gùn lé òwe Yorùbá pé, bí ọmọdé bá júbà òkìtì, yóò roko dalẹ̀. Nínú orin àti ètò ìrúbọ tí àwọn èwe gbé kale lóko ìwádìí tí a lọ, a rí i pé ohun àkọ́kọ́ tí wọ́n ń kọkọ ṣe ni ìjúbà. Àrokò méjì ni a kíyèsí pé wọ́n ń fi èyí pa. Lọ́nà àkọ́kọ́, wọ́n ń lò ó láti rawọ́ ẹ̀bẹ̀ sí àwọn Òrìṣà àti àwọn àgbààgbà tó jù wọ́n lọ ṣáájú ètò irúbọ wọn. lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, wọ́n ń fi ìjúbà yìí ṣe kóríyá fún àwọn Òrìṣà náà àti àwọn àgbààgbà tí wọ́n ń júbà wọn.

## Ìwúre

Àrokò tí àwọn olùsìn Òrìṣà Èwe ń fi ìjúbà àti ìwúre pa láwùjọ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú jọra díẹ̀, ṣùgbọ́n, ìyàtọ̀ wà láàrin wọn. Ohun tó pa ìwúre àti ìjúpà pọ̀ ni pé, nínú ìhun afọ̀ ìjúbà, àwọn apohùn máa ń júbà fún Olódùmarè, Òrìṣà, àwọn ẹ̀mí-àìrí àti àwọn àgbààgbà àwùjọ wọn ṣáájú kí wọ́n tó gba ìre lọ́dọ̀ àwọn tí wọ́n júbà wọn náà. Lọ́pọ̀ ìgbà, burè tó máa ń tẹ̀ lé ìjúbà nínú ìhun afọ̀ ìjúbà àti ìwúre ni a ti máa ń rí ìwúre. Ìdí ni pé, wọ́n fi ìjúbà da omi tútù ṣáájú, kí wọ́n lè tẹ ilẹ̀ tútù. Ẹ jẹ́ kí á fi àyọlò ìsàlẹ̀yìí ṣe àpẹẹrẹ ohun tí à ń sọ gan-an:

Lílé: É é é !!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ

Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fú wa oo
Ayéelé o o o
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fú wa oo
Láráagbó bá waa wò wún dàgbàà
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run lóó fi fúliii
Ègbè: Ayééléé é!!!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fú wa oo
Ẹ̀dá wa bá waa wò wún dàgbàà
Lílé: É é é !!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fú wa oo
Ayéelé o o o
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fú wa oo
Ẹ̀dá wa bá waa wò wún dàgbàà
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run lóó fi fúliii
Ègbè: Ayééléé é!!!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fú wa oo
Ẹ̀dá wa bá waa wò wún dàgbàà
(Lílé:É é é !!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fún wa oo
Ayéelé o o o
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fún wa oo
Láráagbó bá waa wò wọ́n dàgbàà
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run lóó fi fúnniii
Ègbè: Ayééléé é!!!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fún wa oo
Ẹ̀dá wa bá waa wò wọ́n dàgbàà
Lílé: É é é !!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
Ṣèb Ọ́lọ́run ló fi fún wa oo
Ayéelé o o o

Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
ṢèbỌ́lọ́run ló fi fún wa oo
Ẹ̀dá wa bá waa wò wọ́n dàgbàà
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
ṢèbỌ́lọ́run lóó fi fúnniii
Ègbè: Ayééléé!!!
Ẹ̀bùn àrà lọọmọ
ṢèbỌ́lọ́run ló fi fún wa oo
Ẹ̀dá wa bá waa wò wọ́n dàgbàà)

Nínú orin àwọn Alárágbó tí wọ́n ń kọ lẹ́yìn ìrúbọ àti àwọn ètùtù tí wọ́n ṣe nídìí Òrìṣà Alárágbó ni wọ́n ti kọ orin yìí. A lo orin òkè yìí láti ṣe àfihàn ìgbésẹ̀ tó tẹ̀ lé ìwúre àwọn Alárágbó ní ojúbọ Alárágbó, tí àwọn ọlọ́mọwẹ́wẹ́ àti àwọn aláboyún náà fi ìdùnnú wọn hàn sí ìrúbọ àti ètùtù tí wọ́n ṣe náà. Ní ìlà àkọ́kọ́ àyọlò orin Alárágbó tó wà lókè yìí, ó hàn pé àwùjọ àwọn alábiyamọ ni agbo Ẹgbẹ́ Alárágbó jẹ́. Ìwádìí tilẹ̀ fi yé wa pé, ohun méjì pàtàkì jù lọ ló kan àwọn Alárágbó yìí nínú àpéjọ wọn. Ohun àkọ́kọ́ ni pé, wọ́n máa ń kàn sí àwọn Èwe-ọ̀run láti wá sí ayé wá dara pọ̀ mọ́ àwọn. Ohun kejì ni pé, wọ́n máa ń kàn sí àwọn Èwe-ọ̀run láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún wọn lórí ìṣòro tí wọ́n bá ní. Nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá lápapọ̀, yàtọ̀ sí àlàyé tí àwọn Alárágbó ṣe fún wa yìí, Olódùmarè jẹ́ Ẹ̀mí-àìrí kan tó ṣẹ̀dá àwọn ẹ̀mí-àìrí mìíràn sí òde-ọ̀run àti ayé pẹ̀lú àwọn nǹkan mìíràn tí kì í ṣe ẹ̀mí-àìrí. Ìgbàgbọ́ nínú Ọlọ́run àti àwọn ẹ̀mí-àìrí wọ̀nyí ló mú kí àwọn Yorùbá gbára lé wọn nínú ìwòsàn ṣíṣe, nítorí wọ́n gbà pé ọ̀rọ̀ àìsàn mìíràn kọjá ìlò ewé àti egbògi nìkan. Ajíbádé (2006:197) tilẹ̀ fi yé wa pé:

> Among the Yorùbá, the associated with the use of herbs and nature for curing all manners of diseases is Ọ̀sanyìn. This is not to say that their adherents when confronted with sickness do not call upon other deities in the Yorùbá pantheon.
> (Láwùjọ àwọn Yorùbá, Òrìṣà tí a mọ̀ mọ́ ìlò egbògi àti àwọn ohun alábùdá-àdámọ́ fún ìwòsàn èyíkéyìí ni Ọ̀sanyìn. Èyí kò túmọ̀ sí pé kí wọ́n máà kàn sí àwọn òrìṣà mìíràn ní àkókò tí wọ́n bá kojú ìṣòro àìsàn nínú èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá)

Bí a bá wo àyọlò èrò onímọ̀ yìí nípa ìwòsàn ṣíṣe láwùjọ Yorùbá, ó wà ní ìbámu pẹ̀lú èròǹgbà àwọn olùsìn Òrìṣà Èwè tí a ṣe ìwádìí lórí wọn ní ilẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. Lọ́nà àkọ́kọ́, wọ́n gbàgbọ́ pé ẹ̀mí-àìrí kan ni Ọlọ́run tí Ó sì tún dá àwọn ẹ̀mí-àìrí mìíràn sí òde ọ̀run tí wọ́n pè ní Elérèé ọmọ bí Alárágbó, Kóríkóto, Yemulẹ̀, Ẹgbẹ́ Ọ̀gbà àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ̀ pé, Ọlọ́run ni wọ́n ń ké pè nínú orin wọn bí èyí tí a rí àpẹẹrẹ ìwúre nínú rẹ̀

lókè yìí. Lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, nítorí ọmọ ni wọ́n ṣe ń wúre náà gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn ní ìlà kìn-ín-ní títí dé ìlà tó kẹ́yìn àyọlò náà.

Èyí ló mú wọn kọ́kọ́ dárúkọ Olódùmarè, gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí wọ́n ṣe fún wa pé Olódùmarè ló dá àwọn Òrìṣà tí àwọn ń sìn, Òun náà ló sì yẹ kí àwọn kọ́kọ́ máa kì ṣáájú àwọn Òrìṣà náà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi rawọ́ ẹ̀bẹ̀sí Ọlọ́run láti ìlà kẹfà àyọlò afọ̀ ìwúre òkè yìí títí dé ìlà kẹsàn-án. Ìlà kẹwàá ni wọ́n ti béèrè ohun tí wọ́n fẹ́ gan-an lọ́wọ́ Ọlọ́run. Èyí túmọ̀ sí pé, ìlà kẹfà sí ìlà kẹsàn-án jẹ́ àrokò ìpè, tí ìlà kẹwàá tó tẹ̀ lé àwọn ìlà mẹ́rẹ̀ẹ̀rin (6-9) náà jẹ́ àrokò ẹ̀bẹ̀. Ẹ wo ohun tí à ń sọ nínú àtẹ ìsàlẹ̀yìí:

Ìfọ̀rọ̀pàrokò nínú ìwúre

Ìpè Ẹ̀bẹ̀

Àṣẹ

Ìgbàgbọ́ nínú ìjẹ́hẹn

Àtẹ 1: Ìhun Ìfọ̀rọ̀pàrokò nínú Èdè Ìwúre

Nínú àtẹ òkè yìí, aṣafọ̀ tó ń lo èdè ìwúre yóò mú àrokò ìpè ní ọ̀kúnkúndùn, kí ó lè ní àǹfààní láti pa àrokò ẹ̀bẹ̀sí ẹ̀mí-àìrí tó ń wúre sí. Lẹ́yìn náà ni abala ìhun àrokò àṣẹ tí ó fi ìgbàgbọ́ aṣafọ̀ hàn pé àwọn ẹ̀mí-àìrí náà ti gba àrokò méjèèjì tí òun pa ránṣẹ́ sí wọn. Bí a bá tilẹ̀ wo ìhun afọ̀ ìwúre tó wà lókè yìí láti ìlà kọkànlá títí dé ìlà ogún, aṣafọ̀ kọ́kọ́ pàrokò ìpè ránṣẹ́ sí Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀dá-àìrí kan tí wọ́n gbàgbọ́ pé yóò ṣe oore fún àwọn, wọ́n sì tún parokò sí Láráagbó náà. Léyìn náà ni wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣàlàyé èròǹgbà wọn fún àwọn tí wọ́n perí wọn yìí. A óò rí i pé ìhun afọ̀ náà kún fún ìpàrokò ẹ̀bẹ̀ láti fi àṣẹ sí ohun tí wọ́n ń fẹ́ lọ́dọ̀ àwọn Òrìṣà tí wọ́n ń wúre sí náà. Fún ìdí èyí, èdè ìpàrokò nínú afọ̀ ìwúre kò ní kókó-èrò tó ju pípe ìpọ̀nrí àwọn ẹ̀mí-àìrí kan àti ìrawọ́ ẹ̀bẹ̀ sí wọn lórí èròǹgbà wọn lọ. Àwọn kókó-èrò méjèèjì yìí ló ṣe pàtàkì nínú ìhun afọ̀ ìwúre. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé, kò sí abala tí àwọn kókó-èrò ìfọ̀rọ̀pàrokò-ìwúre yìí kò ti lè wáyé nínú ìhun afọ̀, pàápàá afọ̀ ìwúre.

## Èdè Oríkì

Nínú àwọn ìpohùn tó jẹ mọ́ Òrìṣà Èwe tí a ṣe ìwádìí lé lórí, àpẹẹrẹ oríṣìí ẹ̀yà Oríkì mẹ́ta ló fi ara hàn jù lọ. Bí a ti rí ìhun èdè Oríkì nínú orin tí wọ́n ń kọ, náà ni a rí i nígbà tí wọ́n ń ṣe ìwúre. Oríṣìí ẹ̀yà Oríkì tí a rí tọ́ka sí ni Oríkì Òrìṣà, Oríkì-Orílẹ̀ àti Oríkì ìdílé. Ẹ wo àpẹẹrẹ àyọlò tó wà nísàlẹ̀ yìí:

Lílé: Ọlọ́run ìbà
Ìbà là fòlí jú o
Ọlọ́run ìbà o o
Ìbà là fòlí jú o
A júbà Rẹ lòlí
Kíìba waà ṣẹẹ ò ò
Ègbè: Ọlọ́run ìbà
Ìbà là fòlí jú o
Ọlọ́run ìbà o o
Ìbà là fòlí jú o
A júbà Rẹ lòlí
Kíìba waà ṣẹẹ ò ò
Lílé: Ìwọ lỌba à à
Ìwọ lỌba
BỌ́ba ayé kọ̀ wá
Tòde-ọ̀run ò lí kọ̀ wá o o
Èè è è
Ègbè: Ìwọ lỌba à à
Ìwọ lỌba
BỌ́ba ayé kọ̀ wá
Tòde-ọ̀run ò lí kọ̀ wá o o
Èè è è
Lílé: Ọba lòlí
Ọba lànáá
Ọba lọjọ́ gbogbo
A-jí-pọjọ́-ikú-dàà
Mo mẹ̀ẹ̀ júbà Rẹẹ ò ò
Ègbè: Ọlọ́run ìbà
Ìbà láà fòlí jú o o
Ọlọ́run ìbà o o
Ìbà láà fòlí jú o
A júbà Rẹ lòlí
Kíìba waà ṣẹẹ ò ò
Lílé: Lákáayé Ọṣìn Imọlẹ̀ẹ̀
Ègbè: Ẹbọra okooo!!!
Lílé: Ọlákáayé é é
Ò-lómi-lilé-fẹ̀jẹ̀-wẹ
Ọ̀-láṣọ-ilé-fimọ̀-boora
Mẹ́ẹ̀ fẹ̀jẹ̀ èmi wẹ ò ò
Ègbè: Ọlọ́run ìbà
Ìbà láà fòlí jú o o

| | |
|---|---|
| | Ọlọ́run ìbà o o |
| | Ìbà láà fòlí jú o |
| | A júbà Rẹ lòlí |
| | Kíìba waà ṣẹ̣ẹ ò ò |
| Lílé: | Láàlú Òkiri Òkò |
| | Látọọpa |
| | Abáliwọ́nràn-àn |
| | Báli-wọ́nràn-àn |
| | Bá ò rí dá áá |
| Ègbè: | Gbé e é rì ì ì!! |
| Lílé: | Fòlí jì mí ò ò |
| Ègbè: | Ọlọ́run ìbà |
| | Ìbà láà fòlí jú o o |
| | Ọlọ́run ìbà o o |
| | Ìbà láà fòlí jú o |
| | A júbà Rẹ lòlí |
| | Kíìba waà ṣẹ̣ẹ ò ò |
| (Lílé: | Ọlọ́run ìbà |
| | Ìbà la fòní jú o |
| | Ọlọ́run ìbà o o |
| | Ìbà la fòní jú o |
| | A júbà Rẹ lónìí |
| | Kíbàa wa ó ṣẹ̣ẹ ò ò |
| Ègbè: | Ọlọ́run ìbà |
| | Ìbà la fòní jú o |
| | Ọlọ́run ìbà o o |
| | Ìbà la fòní jú o |
| | A júbà Rẹ lónìí |
| | Kíbàa wa ó ṣẹ̣ẹ ò ò |
| Lílé: | Ìwọ lỌba à à |
| | Ìwọ lỌba |
| | BỌ́ba ayé kọ̀ wá |
| | Tòde-ọ̀run ò ní kọ̀ wá o o |
| | Èè è è |
| Ègbè: | Ìwọ lỌba à à |
| | Ìwọ lỌba |
| | BỌ́ba ayé kọ̀ wá |
| | Tòde-ọ̀run ò ní kọ̀ wá o o |
| | Èè è è |
| Lílé: | Ọba-lónìí |
| | Ọba-lànáá |

| | |
|---|---|
| | Ọba-lọ́jọ́-gbogbo |
| | A-jí-pọjọ́-ikú-dàà |
| | Mo màà júbà Rẹẹ ò ò |
| Ègbè: | Ọlọ́run ìbà |
| | Ìbà laa fòní jú o o |
| | Ọlọ́run ìbà o o |
| | Ìbà laa fòní jú o |
| | A júbà Rẹ lónìí |
| | Kíbàa wa ó ṣẹẹ ò ò |
| Lílé: | Lákáayé Ọṣìn Imọlẹ̀ẹ̀ |
| Ègbè: | Ẹbọra-Okooo!!! |
| Lílé: | Ọlákáayé é é |
| | Ò-lómi-nílé-fẹ̀jẹ̀-wẹ̀ |
| | Ọ̀-láṣọ-nílé-fimọ̀-boora |
| | Má mà fẹ̀jẹ̀ èmi wẹ̀ ò ò |
| Ègbè: | Ọlọ́run ìbà |
| | Ìbà laa fòní jú o o |
| | Ọlọ́run ìbà o o |
| | Ìbà laa fòní jú o |
| | A júbà Rẹ lónìí |
| | Kíbàa wa ó ṣẹẹ ò ò |
| Lílé: | Láàlú Òkiri Òkò |
| | Látọọpa |
| | Abániwọ́nràn-àn |
| | Báni-wọ́nràn-àn |
| | Bá-ò-rí-dá-á-á |
| Ègbè: | Gbé e rìn síwájú o o!! |
| Lílé: | Fòní jìn mí ò ò |
| Ègbè: | Ọlọ́run ìbà |
| | Ìbà laa fòní jú o o |
| | Ọlọ́run ìbà o o |
| | Ìbà laa fòní jú o |
| | A júbà Rẹ lónìí |
| | Kíbàa wa ó ṣẹẹ ò ò) |

Nínú àyọlò òkè yìí, a rí oríkì àwọn Òrìṣà àti ti Ọlọ́run níbẹ̀. Orin ni apohùn yìí ń kọ ní ojúbọ Yemulẹ̀lẹ́yìn tí wọ́n rúbọ tán, tí àríyá sì bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Àrokò tí apohùn yìí fi èdè Oríkì tó hàn nínú afọ̀ náà pa ni kóríyá láti pe ìpọ̀nrí àwọn Òrìṣà náà fún ìrànlọ́wọ́ lórí ohun tí wọ́n ń fẹ́. Ìdí nìyí tí ó fi ki Olódùmarè láti pè É ní orúkọ àpèjẹ́ Rẹ̀. Onírúurú orúkọ tí àwọn Yorùbá ń pe Olódùmarè pọ̀, àpapọ̀ wọn sì ni oríkì Ọlọ́run, tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sì ní ìtumọ̀. Bí a bá wo àwọn

orúkọ Ọlọ́run tí aṣafọ̀ yìí fi ki Oríkì Rẹ̀, ó túmọ̀ sí pé Ọlọ́run ju gbogbo ẹ̀dá ayé àti ọ̀run lọ. Ní ìlà kẹtàlá sí ìlà kẹtàdínlógún àyọlò náà, ọ̀kọrin yìí ki Ọlọ́run ní Ọba tó ju ọba ayé lọ, ó sì là á mọ́lẹ̀nínú orin náà pé, bí gbogbo ọba ayé bá kọ òun sílẹ̀, tí Ọba Ọ̀run (Ọlọ́run) kò kọ òun sílẹ̀, àbùṣe bùṣe. Kódà, ó fi dá ara rẹ̀ lójú pé Ọlọ́run kò lè kọ òun sílẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé, bí Ògún ẹni bá dáni lójú, à á fi gbá orí ni. Ìgbàgbọ́ tí gbogbo àwọn olùsìn Òrìṣà Èwe yìí ní sí Olódùmarè jinlẹ̀, ó sì fi wọ́n lọ́kàn bale púpọ̀ lórí ohun tí wọ́n ń ṣe.

Láti ìlà kẹrìnlélógún àyọlò òkè yìí dé ìlà ọgbọ̀n ni ọ̀kọrin yìí ti ki Oríkì Ọlọ́run gan-an, tí ó sì ṣe àpọ́nlé Rẹ̀ dáadáa. Bákan náà ni ọ̀kọrin yìí ki Ògúnlákáayé láti ìlà kẹrìndínlógójì sí ìlà kejìlélógójì àyọlò orin náà. Lẹ́yìn Ògúnlákáayé ni wọ́n ki oríkì Èṣù Láàlú. Oríkì tí wọ́n ki Èṣù yìí jẹ́ ìpàrokò ẹ̀bẹ̀ láti dènà ìkà àti ìjìyà tí Èṣù máa ń ṣe fún ènìyàn. Wọ́n gbàgbọ́ pé, bí àwọn kò bá fi oríkì yẹn ki Èṣù, bí Èṣù bá bínú sí àwọn, ewu ń bẹ fún wọn lórí gbogbo ètùtù tí wọ́n ṣe. Ìdí gan-an nìyí, tí èdè ìjúbà àti ìwúre fi papọ̀ mọ́ èdè Oríkì nínú irúfẹ́ àwọn ìpohùn báyìí, gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn ní ìlà kẹrìndínlọ́gọ́ta sí ìlà tó kẹ́yìn àyọlò òkè yìí.

## Àgbálọgbábọ̀

Ìwádìí yìí ṣe àgbéyẹ̀wò ipa àti ojúṣe àwọn ọmọdé nínú àṣàyàn Òrìṣà Èwe ní ilẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú. Èyí fún wa ní àǹfààní láti ṣe àwárí ìmọ̀ nípa bí ètò ìbọ àwọn Òrìṣà Èwe wọ̀nyí ti ní ipa lórí ètò ìgbé ayé àwọn tó ń bọ ọ́. Abala ibi tí a dojú ìwádìí yìí kọ láti ṣe àwárí ìmọ̀ ni ìtúpalẹ̀ àwọn ìpohùn tí wọ́n ń lò nínú ìbọ àti akitiyan àwọn Àwòrò pẹ̀lú àwọn AbọrẹÒrìṣà Èwe náà lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan. Ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ipò tí àwọn Yorùbá fi àwọn ọmọ wọn sí nínú ọdún ìbílẹ̀ wọn ṣe pàtàkì. Èròǹgbà àwọn Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú lórí ipò tí wọ́n fi àwọn ọmọdé sí nínú àṣàyàn àwọn Òrìṣà Èwe fi hàn pé, wọn kò fẹ́ kí ẹ̀sìn ìbílẹ̀wọn parun. Iṣẹ́ yìí tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, ipò pàtàkì ni ọdún ìbílẹ̀ wà nínú ètò ìgbé ayè àwọn Yorùbá lápapọ̀. Ìdí pàtàkì tí wọ́n fi ń ṣe ọdún ìbílẹ̀ ni ẹ̀sìn tí wọ́n ń sìn. Lááríjà ẹ̀sìn àwọn Yorùbá náà ní í ṣe pẹ̀lú gbogbo ètò ìgbé ayé wọn. Ọ̀kan pàtàkì lára ètò ìgbé ayé wọn náà ni ọmọ bíbí àti ìtọ́jú ọmọ. Èyí wà lára ìdí tí ètò ọmọ bíbí fi fara hàn nínú ìhun àwọn ìbọ òrìṣà tí àwọn Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú ń sìn nínú àwùjọ wọn.

## Ìwé-ìtọ́kasí


Abọ́dúndé, Titus O. (1975): *Lítíréṣọ̀ Alohùn nílẹ̀ Yorùbá*. Department of African Languages and Literatures, O.A.U, Ilé-Ifẹ̀.

Adéoyè, C. L. (1979), Àṣà àti Ìṣe Yorùbá: Ìbàdàn: Oxford University Press.

Ajíbádé, G.O (2005): “A socio-cultural study of Àbíkú Songs in Yorùbá Land”, *Ntama Journal of Music and Popular Culture*, University of Mainz.

Ajíbádé, G.O (2008): "Representation of Gender Discourse in the Poetry of Akínwùmí Ìṣọ̀lá". In: Akíntúndé, Akínyẹmi and Toyín Falola (eds): *Emerging Persspectives on Akínwùmí Ìṣọ̀lá*, Trenton: African World Press/ The Red Sea Press, 273-287.

Ajíbádé, G.O (2009): *Finding Female Voice: A Socio-Cultural appraisal of Yorùbá Nuptial Poetry*. Germany RUDIGER KOPPEVERLAG.

Ajíbádé, G.O. (1999): "Yorùbá Women Govern their Men: A Socio-Religious Approach to Feminism" *Ifẹ̀ Social Sciences review,* Ilé-Ifẹ̀: Ọbafẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, 17, 2, o.i, 194-203.

Ajíbádé, G.O. (2001): "A Sociological Analysis of Yorùbá Male Personal Oríkì (Oríkì Àbísọ)" *Ifẹ̀ Journal of Theory and Research in Education (IJOTRE),* O.A.U. Ifẹ̀, 6 (1): 90-96.

Ajíbádé, G.O. (2003). "Àgbéyẹ̀wò Awo Ọ̀ṣun àti Àwùjọ Òṣogbo nínú Ewì àti Àwòrán Ọ̀ṣun". Ph.D. Thesis, Department of African Languages and Literatures. Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Allport, G. W. (1985). *The Modern Roots of Social Psychology*. Middletown:

Amber, G. àti Haque, M. (2004). "Socio-Semiotics from Islamic Perspective: Contributions of Early Muslim Scholars and Challenges to Contemporary Muslim Psychologist" nínú *Journal of Religion and Health*. Vol. 43, no.4 (Winter, 2004) o.i 357-377.

Àrẹ̀mú, A. (1974*). Àṣàyàn Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn: O.U.P.

Bámidélé, L. O (2000): *Literature and Sociology*, Lagos. Stirlig-Horden Publishers Nig. Ltd.

Dáramọ́lá, O. àti Jéjé, A. (1967). Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá. Ìbàdàn: Oníbọn-Òjé Press and Publishers.

Fánilọ́lá, K. A. (1989), "Gbàǹjo!!! Tíọ́rì fún Lítíréṣọ̀ Yorùbá" nínú *YORÙBÁ: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*. Special Edition o.i 30-47.

Finnegan, R. (1970): *Oral Literature in Africa*. London, Glasgow. Oxford University Press.

Gergen, Keneth J. (1973), Gergen, Keneth J. (1973). *Socio-Semiotics Evaluation: A Differential Diagnosis*. New York. Academy of Sciences Coltheart.

Kassin, S. àti Fein, S. (1978). *Social Psychology*. Indiana: Charles Hartford.

Ládelé, T.A, Mustapha, O., Awórìndé, A. I, Oyèrìndé O., àti Ọlátúnbọ̀sún, O. (1986). Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Lagos: Macmillan Nig. Publishers.

Moronkọ́lá, M. (2002). "Yorùbá Traditional Physical and Health Education for Natural Development" nínú Ọ̀jẹ́lábí, O.A *Physical and Health Education in Nigeria*. Lagos. Tomtak Printing Press.

Ọlájubù, O. (1972): Àkójọpọ̀ Ewì Egúngún, Longman Nig. Ltd.

Ọlátúnjí, Ọ. (1984), *Features of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn U.P.L

Owólabí, O., Táíwò, O., Báyọ̀, A., Ọlábímtán, A. (1985), Ìjìnlẹ̀ Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ìwé kìíní. Lagos: Evans Brothers Nigeria Limited.

Oyèwùsì, J. A. (1980), *Ogójì Eré Òṣùpá*. Lagos: Thomas Nelson Nig Ltd.

Sewell, W. H. (1989). *Semiotics and Social Relations: An Introduction*. London: Ashgate Publishing.

Triplett, Norman (1990). *Binding Mindsets*. Routledge. Harvard University Press.

Túgbìyèlé, E. A. (1948). Àwọn Àlọ́ Àpamọ̀ Yorùbá. Abẹ́òkúta: De Cornerstone Publications.

Walter, M. G. (1998). "Alienation in Mass Society: some causes and Responses" nínú *Sociology and Semiotic Research* Vol. 49 no.2 o.i 115-147.